**Ose Kefa: Osu Keji, Ojo Keje, 2016**

**Akori Oro: Kiyesi, mo duro li enu ilekun, mo si nkan ilekun –** Part 1

**Eko Kika: Ifihan 3: 14-22**

**Afihan**

Mo duro ni enu ilekun, mo si nkan ilekun ni Oluwa wi. Nje kini ilekun, ilekun je igi tabi irin ti afi se oju ona abawole si ibi kolofin kan ti o le fi aye gba enia lati wole, ti o si tun le ma jeki enia wole. Siwaju si ilekun je ohun ti ko duro si oju kan ti o ma nsi si inu tabi si ode/ita.

Eyi tumo si wipe Oluwa wa ni enu ona, o si nkakun lati wole wa sinu aiye wa.

**<u>Iru awon ilekun ti a daruko ninu Bibeli</u>**

Ao soro nipa awon oniruru ilekun ti a daruko ninu bibeli lati fi oye eko ti a fe ko ye wa. Lehin eyi ao wa mu iru ilekun ti a fe fi se eko ojo isinmi.

**<u>Ilekun ete tabi enu wa:</u>** Ninu iwe Orin Dafidi, oba Dafidi be Oluwa wipe ki o fi eso si enu ohun ki ohun le ma se akoso ahon ohun, ki o si pa ilekun ete ohun mo, ki ohun ma ba so oro alaini-rori jade lati enu ohun. **Orin Dafidi 141: 3**. Nitori idi eyi ara mi ninu Oluwa, e bere lowo Olorun ki o yan eso si enu yin, ki o si yan oluso si ilekun ete yin toripe iku ati iye mbe ni ipa ahon: awon eniti o ba si nlo yio je ere re. **Owe 18:21.**
E kiyesara fun awon onise ibi ki won ma ba tan yin kuro ni ona otito nipa oro didun won. Ninu iwe **Mika 7: 5.** O se ikilo pataki wipe ki a mase gbekele enikeni ayafi Olorun, ki a masi se ni ireti ninu enia

eleran ara. Ni afikun ki a ma mo iru oro ti ao so fun awon enia, kosi bi enia na tile sunmo o to, bi o tile je eniti e jijo nse ere ikoko mase tu asiri re fun. Bi o ko ba fi eti si oro yi, ki o si mu lo, ohunkohun ti o ba sele si o, ki o ma bojuto.

**Ilekun Igbagbo:** Paulu aposteli ninu irinajo ise iranse re rohin bi Oluwa ti si ilekun igbagbo fun awon keferi, ki awon na le gbagbo ki won si je alabapin ninu Ihinrere ati Igbala nipase Jesu Kristi Oluwa wa. **Ise awon Aposteli 4: 27**. Mo fe ki gbogbo okan ro arojinle nipa ore ati ise nla ti Olorun ti se ninu aiye won: nitorina ki awon se bi oti ye, ki won si se awari ni kikun ilekun igbagbo ti Oluwa ti si fun awon alaigbagbo, ki a ba le ti ipa be gba okan won la.

**Ilekun Igbala:** Olorun pase fun awon omo Israeli igbaani wipe ki won fi eje kun ara aterigba ati opo iha mejeji enu-ona ile won : ki Oluwa le rekoja awon enu-ona won, nipa sise eyi ki yio si jeki apanirun wole won lati kolu won tabi lati pa won. **Eksodu 12: 22-23**. Igboran si ase Oluwa se igbala okan awon omo Israeli ni ilu Goseni ni ile Egipti ni igbati awon ara Egipti si padanu emi won lopolopo. Fun idi eyi, e jeki a ma tele ohun Oluwa Olorun wa ni gbogbo igba, bi oro tabi ase re ba tile ju oye wa lo, dandan ni lati mu se.

**Ilekun Irapada:** A ni lati mo wipe Jesu Kristi nikan ni ilekun irapada: atipe gbogbo okan ti o ba gba inu ilekun yi koja, ti rekoja lati inu iku sinu iye , eyiti o tumo si wipe a ti ra iru okan be pada gegebi bibeli se so/wi. **Johannu 10: 7-9**. Ara e jeki a ronu jinle nipa oro yi ki a si di Jesu Kristi mu gidigidi nitori ohun ni ayako iwe ti ao fi gba wa si aiye ti nbo. A ni lati gba ni aise iyemeji wipe ohun ni Oluwa ati Olugbala ti o le jeki a di eni ikaye ni ikehin, ki a si jogun ile ologo.

**Ilekun aaye:** Oluwa si ilekun aaye fun Paulu aposteli ni ilu Efesu ati ilu Troa. Pelu iranlowo Oluwa Paulu lo awon aaye yi lati jere okan sinu ijoba Olorun. **1 Korinti 16: 8-9, 2 Korinti 2: 12**. E jowo e jeki a se

afarawe Paulu ki a mase so aaaye tabi akoko ti o ba si sile nu bikose ki a lo lati wasu oro Olorun: lati koni leko, lati jere okan fun Oluwa ati lati fi igbagbo wa yangan ni gbangba ni ai-tiju eyiti yio jeki awon Orun fi ere fun ise wa.

**Ilekun Ore-ofe:** Jesu Kristi nikan ni o ni kokoro Dafidi, ohun nikan ni eniti o le si ilekun ti enikeni kosi le ti ilekun ti o ba si. Ti Kristi ba ti ilekun kosi eniti o le si, O lo kokoro Re lati si ilekun ore-ofe fun ijo ti o wa ni Filadelfia. **Ifihan 3: 7-8**. Mo gbadura wipe ilekun ore-ofe ati itesiwaju ti Oluwa si ninu aiye wa, ese ati esu koni ti ilekun na. Ni afikun Kristi yio lo kokoro Dafidi Re lati ti ilekun ekun ati ibanuje ti nbe ninu aiye wa.

**Ilekun Emi/Ifihan:** Jesu Kristi mu oro Re se ninu aiye Johannu aposteli, eyiti o wipe "loto ni mo wi fun yin, elomiran wa ninu awon ti o duro nihinyi, ti ki yio ri iku, titi won yio fi ri Omo-enia ti yio ma bo ni ijoba re". **Matteu 16: 28**. Oro yi wasi imuse ni igbati Johannu ri ti ilekun kan si sile ni orun, ti ohun ipe si wipe; goke wa ihin, emi o si fi ohun ti yio hu lehin-ola han o. **Ifihan 4: 1**. Eniti o se ifihan asiri orun fun Johannu aposteli nbe laaye, yio fi ebun Emi Mimo kun aiye wa, bi a ba gboran,ti a si ni iforiti, ti a ko si ye ese wa.